# ÀKỌ́RỌ̀ ATI ÀRỌ̀KÚRỌ̀ ÒJÒ

## Joẹli 2:21-32; Iṣe Awọn Apọsteli 2:1-47

## ẸKỌ 66 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ṣugbọn ẹnyin ó gbà agbara, nigbati Ẹmi Mimọ́ ba bà le nyin: ẹ o si ma ṣe ẹlẹri mi ni Jerusalẹmu, ati ni gbogbo Judea, ati ni Samaria, ati titi de opin ilẹ aiye" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:8).**

**I Asọtẹlẹ Joẹli**

1 Akoko iyin ati inu didun yoo de, Joẹli 2:21, 23, 26; Iṣe Awọn Apọsteli 2:46, 47
2 Ileri akọrọ ati arọkuro ojo ni o mu inu didun wá, Joẹli 2:23
3 Yoo jẹ́ akoko igboya – "Oju kì o si tì awọn enia mi lai," Joẹli 2:26, 27; Iṣe Awọn Apọsteli 4:13; 14:3
4 A o tú Ẹmi Ọlọrun jade si ara eniyan gbogbo, Joẹli 2:28, 29; Iṣe Awọn Apọsteli 2:4

**II Ọjọ Pẹntekọsti**

1. Eyi li ọ̀rọ ti a ti sọ lati ẹnu woli Joẹli wá," Iṣe Awọn Apọsteli 2:16
2. Isọdimimọ́ ti wọn ti ni mú ki gbogbo wọn wà ni iṣọkan, Iṣe Awọn Apọsteli 2:1; Johannu 17:11-23; Heberu 2:11
3. A tú Ẹmi Mimọ́ jade pẹlu ami fifi èdè fọ̀, Iṣe Awọn Apọsteli 2:2-13
4. Peteru waasu pẹlu igboya nipa ifororoyan Ẹmi Mimọ́, Iṣe Awọn Apọsteli 2:14-36
5. Ẹmi Ọlọrun mu irobinujẹ fun ẹ̀ṣẹ wọ inu ẹgbẹẹdogun ọkàn, wọ́n si ronupiwada, Iṣe Awọn Apọsteli 2:37-47
6. A tú Ẹmi Mimọ́ jade sii, ami kan naa si n tẹle e, Iṣe Awọn Apọsteli 10:46; 19:6

**III Akọrọ ati Arọkuro Ojo**

1. Akọrọ ojo maa n rọ ni akoko fífún irugbin, Deuteronomi 11:14; Hosea 6:3; Joẹli 2:23
2. Arọkuro ojo maa n dé ni ṣaaju igba ikore, Joẹli 2:23; Jeremiah 5:24
3. Arọkuro ojo ti Ẹmi rọ̀ ni ọjọ kin-in-ni oṣu ti awọn Ju n pe ni "Abibu" eyi ti i ṣe April ti wa ni 1906, Joẹli 2:23; Jakọbu 5:7; Iṣe Awọn Apọsteli 2:39

## ALAYE

### Ti Ara ati ti Ẹmi

Ni ori keji Iwe Wolii Joẹli ẹsẹ 21-27, Joẹli n sọ nipa awọn ibukun ti ara ti Ọlọrun n tú jade; ṣugbọn ohun ti ara ni a fi i ṣe apejuwe ohun ti ẹmi. Nigba pupọ ninu iṣẹ-iranṣẹ Kristi ni ayé, O fi ohun ti o yi I ká ṣe akawe ẹwa ibukun ti Ẹmi. Ni Palẹstini, akọrọ ojo maa n rọ̀ lati pese ilẹ fun irugbin; arọkuro ojo ni lati mu eso pọ́n fun ikore. Ileri ojo wọnyii n tọka si awọn ibukun ti ara ati ti ẹmi ti Ọlọrun yoo tú jade sori awọn eniyan Rẹ̀.

**"Yio si ṣe, nikẹhin emi o tú ẹmi mi jade si ara enia gbogbo; ati awọn ọmọ nyin ọkọnrin, ati awọn ọmọ nyin obirin yio ma sọtẹlẹ, awọn arugbo nyin yio ma lá alá, awọn ọdọmọ-kunrin nyin yio ma riran: Ati pẹlu si ara awọn ọmọ-ọdọ ọkunrin, ati si ara awọn ọmọ-ọdọ obirin, li emi o tú ẹmi mi jade li ọjọ wọnni" (Joẹli 2:28, 29).**

### Ohun Ọ̀tun

A le ri i pe ifarahan ti o yatọ patapata si eyi ti o ti ṣẹlẹ ri yoo waye nipa bi Ọlọrun ṣe maa n bá awọn eniyan Rẹ̀ lò. Ni igba laelae awọn aṣayan eniyan kan ni a yà sọtọ fun iṣẹ-isin ti ẹmi. Awọn ti a bi ni idile Aarọni ni o gbọdọ jẹ oye alufaa, wọn si maa n ṣe iṣẹ naa, gẹgẹ bi eto ti a fi lelẹ, ni akoko ti o ba kan olukuluku. Ọlọrun tikara Rẹ̀ ni o n pe awọn wolii. Ṣugbọn nihin Ọlọrun dá akoko kan ninu eyi ti Oun yoo tú Ẹmi Rẹ̀ sara eniyan gbogbo. Awọn ọdọmọkunrin ati awọn ọdọmọbinrin, awọn ọmọ-ọdọ ọkunrin ati awọn ọmọ-ọdọ obinrin yoo maa sọtẹlẹ tabi kede otitọ Ihinrere ati imọ Ọlọrun. Eyi yoo jẹ́ igba ti o logo ju lọ! Ninu Iṣe Awọn Apọsteli 2:16 a kà pe ni ọjọ Pẹntekọsti Peteru dide duro o si waasu wi pe, "Eyi li ọ̀rọ ti a ti sọ lati ẹnu woli Joẹli."

### Pẹlu Ọkàn Kan

"Nigbati ọjọ Pẹntekọsti si de, gbogbo nwọn fi ọkàn kan wà nibikan" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:1). Ẹsẹ ọrọ yii fi otitọ pataki kan hàn. A sọ fun wa ninu Heberu 2:11 pe, "Ati ẹniti nsọ-ni di mimọ́ ati awọn ti a nsọ di mimọ́, lati ọdọ ẹnikanṣoṣo ni gbogbo wọn." Ọrọ wọn dọgba, wọn si ni ọkàn kan ati ero kan nipa Ihinrere. Awọn ti a sọ di mimọ́ nikan ni o le wà ni ọkàn kan ni tootọ. Jesu gbadura pe ki a sọ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ di mimọ́ ki a si ṣe wọn ni ọ̀kan. (Wo Johannu 17). Adura yii ti ṣẹ -- a sọ wọn di mimọ́ patapata. Gbogbo wọn wà ni ọkàn kan ni ibi kan.

Awọn miiran wà ti wọn gba ẹkọ isọdimimọ́, ṣugbọn wọn n fi isọdimimọ pe fifi Ẹmi Mimọ́ wọ ni. Iwe Mimọ́ sọ fun wa pe isọdimimọ́ ni iṣẹ iwẹnumọ, sisọ ni di alailabawọn tabi alaileeri patapata eyi ti o n ṣẹlẹ ninu ọkàn lẹyin ti a ti ri igbala. Eyi jẹ iriri ti o daju ti o si n ṣẹlẹ lẹẹkan gbọn ọn, ninu eyi ti a pa ẹṣẹ abinibi inu ọkàn eniyan run. Gẹgẹ bi igbala ti maa n ṣiṣẹ iyipada igbesi-ayé, ti a n ri idariji, ti o si n mu iwa ẹ̀ṣẹ ti ode ara kuro, bakan naa ni isọdimimọ́ maa n mu "aworan Adamu" tabi ẹṣẹ abinibi kuro.

**Agbára**

Isọkalẹ Ifiwọni Ẹmi Mimọ́ jẹ imuṣẹ ileri Jesu, ti O ṣe fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ nigba ti O wi pe "Ṣugbọn ẹnyin ó gbà agbara, nigbati Ẹmí Mimọ́ ba bà le nyin." Agbára! Eyi ṣe pataki gidigidi – agbára! Ki ni anfaani ẹrọ iṣiṣẹ ati iru awọn irinṣẹ ti a so pọ̀ bẹẹ lai si agbára ti yoo mu wọn ṣiṣẹ? Njẹ o ti ri ọkọ oju irin ti a gbé kalẹ? Ohun elo gbogbo ni o pe sara rẹ̀ perepere, ṣugbọn omi kò si ninu ile omi rẹ, iná kò si si ninu ile iná rẹ̀. Ṣugbọn fi omi sinu ile omi ati ina sinu ile ina rẹ, iwọ yoo si ri i pe ẹrọ naa a bẹrẹ si i ṣiṣẹ, ọkọ naa yoo si bẹrẹ si i lọ, ki i si ṣe bẹẹ nikan, yoo tun bẹrẹ si i wọ́ gbogbo nnkan ti a ba so mọ́ ọn. Bi a ba gba agbára lati Oke, ki i ṣe awa nikan ṣoṣo ni yoo gbina, a o si ja si iranlọwọ lati sọ awọn ẹlomiran jí pẹlu. Ki Ọlọrun jọwọ fun wa ni agbára yii lonii!

Ọkàn wa ati agbára wa kò já mọ nnkan kan rara titi di igba ti a ba fi agbára Ẹmi Mimọ́ wọ̀ wa; nigba naa ni gbogbo talẹnti wa, gbogbo ọgbọ́n wa, ati ohun gbogbo ti a ni yoo maa ṣiṣẹ ni iṣọkan pipé pẹlu Ẹmi Ọlọrun. Peteru kan naa ti o sẹ́ Oluwa rẹ̀, ṣugbọn ti o ti pada sọdọ Ọlọrun, ni a ri lẹyin itujade agbára Ẹmi Mimọ́ ti o waasu iyanu nì nipa agbára Ẹmi Mimọ́ ti a rán sọkalẹ lati Ọrun. Ẹgbẹẹdogun ọkàn ni a rapada.

**Fun Wa Lonii**

Awọn miiran wi pe Ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ki i ṣe fun wa lakoko yii, wọn ni a kan fi Ifiwọni Ẹmi Mimọ́ dá Ijọ akọkọ silẹ ni. Peteru waasu pe "fun nyin ni ileri na, ati fun awọn ọmọ nyin, ati fun gbogbo awọn ti o jìna rére, ani gbogbo awọn ti Oluwa Ọlọrun wa ó pè" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:39). Ileri yii jẹ ti olukuluku eniyan titi di ọjọ oni, ti wọn ṣe tan lati mu àṣẹ Ọlọrun ṣẹ.

**Ami Rẹ̀**

Awọn miiran gbagbọ́ pe a le ri Ifiwọni Ẹmi Mimọ́ gbà, ṣugbọn fifi ede fọ̀ ni wọn wi pe kò ṣe pataki. A ka a pe ni Ọjọ Pẹntekọsti gbogbo wọn si kún fun Ẹmi Mimọ́, wọn si bẹrẹ si i fi ède miiran sọrọ gẹgẹ bi Ẹmi ti fun wọn ni ohùn.

Ami fifi ede fọ̀ ni o fi hàn fun awọn Ju pe Ọlọrun rán Ẹmi Rẹ̀ sọkalẹ sori awọn Keferi ni ile Kọrneliu (Iṣe Awọn Apọsteli 10:44). Ọlọrun si n fi Ẹmi Rẹ̀ wọ awọn ti o gbagbọ́ lonii, ami kan naa ni o si n tẹle e – fifi ède titun sọrọ.

Iyatọ ti o yanju gbangba ni o wà laaarin ifiwọni Ẹmi Mimọ́ pẹlu ẹri fifi ede fọ̀ gẹgẹ bi Bibeli ti fi idi rẹ̀ mulẹ ati oriṣiriṣi ẹbùn Ẹmi miiran. Oniruuru ẹbun ni o wà ni tootọ. "Ẹbun ahọn" jẹ́ ọ̀kan, imularada jẹ ọkan, isọtẹlẹ jẹ ọkan. Jijẹ olukọni jẹ ọkan, ẹbun iṣẹ ẹfangẹlisti jẹ ọkan, igbagbọ́ jẹ ọkan, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ṣugbọn iyatọ wà laaarin awọn ẹbùn wọnni ti Paulu sọ nipa rẹ̀ ninu Kọrinti ati fifi ede fọ ti ọjọ Pẹntekọsti. Bi ko ba jẹ bẹẹ awọn ọgọfa ọmọ-ẹyin ni iyara oke i ba gba oriṣiriṣi ẹbun. Nigba ti Olutunu nì de ti a si tú Ẹmi Mimọ́ le wọn lori, ami kan naa ni gbogbo wọn gbà.

**Ju Ni Gbogbo Wọn**

Awọn miiran n wi pe fifi ede fọ̀ ṣe pataki ki awọn eniyan ti o ti oriṣiriṣi orilẹ-ede wá – Mesopotamia, Kapadokia, Libia, Egipti – ba le gbọ́ ọrọ naa. Iṣe Awọn Apọsteli 2:5 sọ fun wa pe Ju ni gbogbo wọn i ṣe, lai si aniani, wọn gbọ́ ede ibilẹ wọn. Nitori naa oriṣiriṣi ede ti wọn sọ wà fun ámi ki i si ṣe lati jẹ ki awọn Ju mọ ohun ti wọn n wí. Iwaasu Peteru ati alayé ti o ṣe ki i ṣe ni oriṣiriṣi ede, ni ede kan ṣoṣo ni. Awọn eniyan naa gbọ́, o si yé wọn.

**Awọn Aláṣerége**

Ọpọlọpọ awọn aláṣerege ni o ti mú ẹgan ba Ihinrere Ojo Arọkuro nipa ifedefọ èké ati aṣerege gbogbo. Awọn eniyan maa n fi ara wọn si iru ipo bayii nigba ti wọn ba n beere fun ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ati iná lai kọ́kọ́ ni iriri isọdimimọ́ patapata. Eṣu maa n gbé ayederu lé ẹnikẹni ti ko ba fẹ gbọran si gbogbo Ọrọ Ọlọrun lọwọ. Bi o ti wu ki o ri, ifiwọni Ẹmi Mimọ́ tootọ wà, lai fi ayederu ti eṣu pè.

**Akọ́rọ̀ Òjò**

Gẹgẹ bi asọtẹlẹ Joẹli, Ọlọrun tu Ẹmi Rẹ̀ sori eniyan gbogbo ni akoko awọn Apọsteli. Eyi ni Akọrọ Ojo ti Ẹmi ti Ọlọrun ti ṣeleri. Ọjọ Pẹntekọsti ni ìbẹ̀rẹ̀, tabi igba gbígbin Ijọ Kristi. Ọlọrun tú Ẹmi Rẹ̀ jade, awọn ọmọ-ẹyin si lọ si ibi gbogbo lọ waasu Ihinrere. A fi idi Ijọ kalẹ o si n gberu fun igba diẹ; lẹyin naa ni "iyapa nì" de ati ìyàn Ẹmi.

**Ojo Arọkuro**

Ki bibọ Jesu lẹẹkeji to ṣẹlẹ ati igba ikore, o ṣe pataki pe ki a sọ Ijọ jí. Ọlọrun ti ṣeleri Ojo Arọkuro.

**"Nitorina ará, ẹ mu sũru titi di ipadawa Oluwa. Kiyesi i àgbẹ a mã reti eso iyebiye ti ilẹ, a si mu sũru de e, titi di igbà akọrọ̀ ati arọ̀kuro òjo" (Jakọbu 5:7).**

Ni April, (oṣu kẹrin ọdun) 1906, ọpọlọpọ awọn ọmọ Ọlọrun tootọ́ ni o wà ni ilu Los Angeles, ni California, America, ninu ile isin gbogbo, ti wọn n gbadura fun itujade Ẹmi ati fun isọji gbogbo agbaye. Iranṣẹ Ọlọrun kan ti o ti ibi isọji Wales wá si Los Angeles rú ifẹ awọn eniyan wọnyii soke lati gbadura. Awọn ẹgbẹ aladura wà kaakiri ile-isin ni ilu yii ati boya ni gbogbo ayé lakoko naa ti wọn n gbadura fun Ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ati fun isọji pẹlu. Ṣugbọn ẹgbẹ́ eniyan kekere kan wa, **awọn ti a ti sọ di mimọ́,** ti wọn fi ohùn ṣọkan lati fi adura ṣọna fun ọjọ mẹwaa fun itujade ifiwọni Ẹmi Mimọ́. Gbogbo wọn wà ni ọkàn kan, wọn si ni ireti pe nigba ti wọn ba ri iriri Pẹntekọsti gbà, wọn o gba ami fifi ede titun sọrọ, gẹgẹ bi ti Iṣe Awọn Apọsteli 2:4. Oluwa fi edidi Rẹ̀ di agbo kekere yii.

Joẹli sọ asọtẹlẹ pe a o fun ni ni Arọkuro Ojo ni oṣu kin-in-ni. Oṣu kin-in-ni awọn Ju ni "Abibu," tabi April ti wa.

Ni ọjọ kẹsan-an oṣu April, (oṣu kẹrin) ọdun 1906, agbára naa sọkalẹ laaarin ipade kan ninu ile kekere kan ni opopo Bonnie Brae nibi ti awọn ẹgbẹ kekere yii pejọ si. Laaarin wọn ni awọn kan ri ifiwọni Ẹmi Mimọ gbà, wọn si fi ede titun sọrọ gẹgẹ bi Ẹmi Mimọ́ ti fun wọn ni ohùn. Agbara nla Ọlọrun fara hàn. Iroyin naa tàn kaakiri. Awọn ọkàn ti ebi n pa bẹrẹ si wá lọpọlọpọ, to bẹẹ ti awọn ile ti a ti n jọsin wọnyii kún to bẹẹ ti àyè kò gbà wọ́n mọ́. Nitori eyi wọn ni lati wa àyè si inu ile kan ti o dabi ibi ti àgbẹ n kore oko si ni ọganran kan ti a n pe ni Azusa; ibi irẹlẹ ni, ṣugbọn nibẹ ni awọn eniyan n ri Ẹmi Mimọ́ gbà.

Ọlọrun n fi Ẹmi Mimọ́ wọ awọn ti o gbagbọ́ sibẹ. A ti fun ni ni Akọrọ ati Arọkuro Ojo. Igba ikore sun mọ́ tosi wa pẹkipẹki. Agbẹ ti o ti n fi suuru duro pẹ titi fun eso iyebiye aye ki yoo tun duro pẹ́ mọ. Jesu n bọ̀ lai pẹ!

**AWỌN IBEERE**

1. Imurasilẹ wo ni o yẹ fun ẹni ti o n fẹ́ gba ifiwọni Ẹmi Mimọ́?
2. Tọka si ẹsẹ Iwe Mimọ lati fi hàn pe fifi ede titun sọrọ jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ẹri gbigba ifiwọni Ẹmi Mimọ́.
3. Njẹ fifi ede fọ̀ ha to lati fi idi rẹ mulẹ pe eniyan ri Ẹmi Mimọ́ gbà?
4. Ẹsẹ Iwe Mimọ wo ni o sọ fun wa pe iriri ifiwọni Ẹmi Mimọ́ yii wa fun wa lonii?
5. Nigba wo ni Akọrọ Ojo ti Ẹmi rọ̀? Nigba wo ni Arọkuro Ojo?
6. Ki ni itumọ "arọ̀kuro ojò ni oṣù ikini?"
7. Bawo ni akọsilẹ Joẹli ṣe ba akọsilẹ ti awọn akọwe Majẹmu Laelae mu?
8. Njẹ àmì fifi ede titun sọrọ nigba ti a ba ri Ẹmi Mimọ́ gbà ha jẹ ọkan naa pẹlu ẹbun ahọn?
9. Fun idi wo ni a ṣe rán akọrọ ati arọkuro ọ̀jọ̀ ti ara?
10. Awọn meloo ni a gbala ni Ọjọ Pẹntekọsti?
11. Awọn meloo ni o ri Ẹmi Mimọ gba ni Ọjọ Pẹntekọsti?